# FÍFI TÍỌ́RÌ ÀṢÀ ÌBÍLẸ̀ ṢE ÌTÚPALẸ̀ EWÌ ÈWE ÌWÒYÍ NÍNÚ EWÌ ÀFÀÌMỌ̀ ÀTI ÀRÒFỌ̀ MÌÍRÀN TÍ AKÍNWÙMÍ ÌṢỌ̀LÁ KỌ

TÁYÉ FATIMA SHEU


## Àṣamọ̀

Àṣà Yorùbá ti ń di àtẹ̀mẹ́rẹ̀ lọ́dọ̀ àwọn èwe ìwòyí, èyí rí bẹ́ẹ̀ látàrí àṣà àtọ̀húnrìnwá àti ìmọ̀ ẹ̀rọ lílò, èyí tí ó ń fi ojoojúmọ́ gbilẹ̀ nínú àwùjọ Yorùbá. Nínú bébà yìí a ṣe ìtúpalẹ̀ Ewì Èwe Ìwòyí tó jẹ́ ọ̀kan lára ewì tó wà nínú ewì "Àfàìmọ̀ àti Àwọn àròfọ̀ Mìíràn" tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ. Tíọ́rì Àṣà Ìbílẹ̀ ni a ṣe àmúlò láti fi la tìfun-tẹ̀dọ̀ iṣẹ́ náà, kókó inú ewì Èwe Ìwòyí àti àwọn ọnà èdè tó súyọ nínú ewì náà. Bákan náà, a ṣe ìtúpalẹ̀ ewì náà pẹ̀lú Tíọ́rì Àṣà Ìbílẹ̀. Ní ìparí, a ṣe àgbálọgbábọ̀ iṣẹ́ náà.


## Ìfáàrà

Nínú èrò àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ kan Ilésanmí (1992:102), Adéoyè (2001) pẹ̀lú Babátúndé (1996). Wọ́n ní

> Àṣà ni ohun gbogbo tó jẹ mọ́ ìgbé ayé àwọn àsèwàdá ènìyàn kan ní àdúgbò kan, ó bẹ̀rẹ̀ lórí èrò wọn, èdè wọn, ẹ̀sìn wọn títí kan ètò ìṣèlú wọn, ètò ọrọ̀-ajé, ìṣẹ̀dá ohun èlò, ìtàn òfin, iṣẹ́, ìrísí, ìhùwàsí, oúnjẹ àti ọ̀nà iṣẹ́ nǹkan.

Àwọn onímọ̀ yìí tẹ̀síwájú pé àyíká pàápàá jẹ́ kókó nínú ohun tí a lè pè ní àṣà àwùjọ kan nítorí pé ojoojúmọ́ ni ọmọ ènìyàn ń yí àyíká rẹ̀ padà nípa lílo tó ń lo nǹkan tí Olódùmarè ṣe lọ́jọ́ sí àyíká tàbí àdúgbò kọ̀ọ̀kan. Bí àṣà àdúgbò ṣe wà bẹ́ẹ̀ ni àṣà àgbáyé lápapọ̀ wà pẹ̀lú. Bákan náà, nínú àlàyé Raji (1993:109), ó ní àwọn àṣà kan wà tó ṣe pé bíná-ń-jó, bójò-ń-rọ̀, wọn kì í yí padà rárá, bí àpẹẹrẹ ìṣẹ̀ṣe, a kò gbọdọ̀ yìí ìṣẹ̀ṣe padà rárá, torí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìṣẹ̀ṣe Yorùbá ni ẹ̀sìn àti àṣà àjòjì ti dorí rẹ̀ kodò, tí a bá tẹ̀lé èrò Raji yìí, a óò ríi pé, ní òtítọ́ àṣà àjòjì ti borí àṣà Yorùbá. Àjàyí (1998) wá tọ́kasí àwọn ohun tó ṣe àkóbá fún àṣà wa, yàtọ̀ sí ọ̀làjú òde-òní, lára àwọn ohun tó mẹ́nu bà ni ẹ̀kọ́ àti ẹ̀sìn ilẹ̀ òkèèrè, púpọ̀ àwọn àgbà tó jẹ́ alákòójọ àti olùpamọ́ àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá

ti kú tán. Ọ̀pọ̀ àwọn òbí ni wọn kò sì ní ìfẹ́ sí àwọn ohun tó jẹ́ tiwa-n-tiwa, èyí rí bẹ́ẹ̀ látàrí àìsí ààyè fún ọ̀pọ̀ òbí, ilé alásookan ni gbogo wa ń kọ́, ẹ̀rọ amóhùn-áwòrán, rẹ́díò àti fóònù alágbèéká tí gba àṣà mọ́ wa lọ́wọ́. Fún ìdí èyí, kò ní yàwá lẹ́nu tí a bá rí ọmọ oníbìí-níran tó ń sìwà hù, tàbí tó ju àṣà rẹ̀ nù, tó sì gbé àṣà alásà wọ̀ bí ẹ̀wù, kò sí ìmúnisìn kan tó tún tayọ èyí.

Iṣẹ́ yìí ṣe àmúlò tíọ́rì àṣà ìbílẹ̀ láti fi ṣe iṣẹ́ abẹ fún ewì tí à ń yẹ̀wò yìí. A ṣe àmúlò tíọ́rì àṣà ìbílẹ̀, torí pé tíọ́rì yìí fi àyè gba ìdáàbòbò, àṣà ìbílẹ̀ àti ìṣẹ̀ṣe àwùjọ kan, fífàyọ àwọn àṣà abaniláyé jẹ́ inú àwùjọ kan, ó sì gba àṣà titun láàyè, pàápàá èyí tó lè mú ìtẹ̀síwájú àti ìdàgbàṣókè bá àwùjọ àti àwọn ènìyàn inú rẹ̀. Ṣùgbọ́n a gbọdọ̀ tàbùkù àwọn àṣà abanilórúkọ jẹ́, àṣà asọni dèrò ẹ̀yìn, àṣà tó lè mú ẹ̀gàn àti ìtìjú bá àwùjọ àti àwọn ènìyàn inú rẹ̀. Kí á sì ṣe àtúnṣe sí àwọn àṣà tó wà nílẹ̀, ni ọ̀nà tí yóò fi mú ìdàgbàṣókè àti orúkọ rere bá àwọn ènìyàn inú àwùjọ.

## Tíọ́rì Àmúlò: Tíọ́rì Ìfojú-Àṣà-Ìbílẹ̀-Wò

Rasteloot, Dorothy Blair ni ó ṣe agbáterù tíọ́rì yìí, ó rí àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun atáyése, tó máa ń tẹ̀ síwájú tàbí tó máa ń dàgbà, àwọn kan gbàgbọ́ nínú àwọn abẹnugan tíọ́rì yìí pé bí àṣà bá ṣe wà náà ni ó gbọdọ̀ wà, a kò gbọdọ̀ bù kún-un, bẹ́ẹ̀ a kò gbọdọ̀ yọ kúrò. Wọ́n rí tíọ́rì àṣà ìbílẹ̀ bí ohun atáyése, wọ́n sì gbàgbọ́ pé iṣẹ́ lítíréṣọ̀ gbọdọ̀ ṣetán láti dá ààbò bo àṣà abínibí.

A ríi kà nínú iṣẹ́ Adéyẹmí (2006) pé àwọn agbáterù tíọ́rì yìí sọ pé iṣẹ́ tí lítíréṣọ̀ máa ń ṣe ni láti dáàbò bo àṣà àti ìṣẹ̀ṣe àwùjọ kan, nítorí náà ohun tó gbọdọ̀ jẹ́ lámèyítọ́

lógún ni ṣíṣe àfihàn irú àwọn àṣà tó súyọ nínú iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀. Adéyẹmí tún tẹ̀ síwájú láti ṣàlàyé ohun tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Wándé Abímbọ́lá sọ nípa àṣà. Ó ní:

> Therefore, in order to evolve an acceptable format for the appreciation of oral literature, we must blend our knowledge of the most up-to-date techniques of literary criticism and stylistics with a thorough understanding of Yorùbá culture. Without this, any critical work is bound to be sterile (1982:78).

Ìtumọ̀:

> Kí á tó lè rí ìlànà lámèyítọ́ lítíréṣọ̀ tí yóò jẹ́ ìtẹ̀wọ́gbà, a ní láti jẹ́ kí ìmọ̀ wa papọ̀ mọ irú ìlànà bẹ́ẹ̀ bí ó ti wù kí ó jẹ́ tí òde-òní tó ní ọwọ́ àṣà Yorùbá nínú. Bí bẹ́ẹ̀ kọ́ òfégè lásán ni iṣẹ́ lámèyítọ́ bẹ́ẹ̀ yóò jẹ́ (1982:78).

Ohun tí Ọ̀mọ̀wé Abímbọ́lá sọ yìí tẹ̀wọ̀n, torí pé kò sí bí a ṣe lè yọwọ́ àṣà kúrò nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá, òpómúléró ni àṣà jẹ́ nínú ìtàn àròsọ, ewì àti eré onítàn Yorùbá. Ònkọ̀wé lítíréṣọ̀ gbọdọ̀ le ṣàwárí àwọn àṣà ìbílẹ̀ tó ti sọnù kí wọ́n sì ṣe àfihàn wọn lọ́nà tí yóò gbé àṣà Yorùbá láruge.

Àmọ́ o, nípa tíọ́rì àṣà ìbílẹ̀ yìí, kinní kan ló ba Àjàò jẹ́, apá kan gùn ju ìtàn lọ. Àléébù rẹ̀ ni pé àwọn agbátẹrù rẹ̀ pín sí méjì. Àwọn apá kìnní rí àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun tí kò gbọdọ̀ yí padà. Àṣà tí kò wúlò fún ènìyàn ni wọ́n gùn lé, àṣà tí kì í fẹ́ ìjà, kì í fẹ́ ìta, kí ènìyàn sá wà nìoju kan ni tiwọn. Ṣùgbọ́n àwọn ìsọ̀wọ́ kejì ni àwọn tó gba àṣà ní atáyéṣe, ìtanijí, tí ó sì tún lè gún àwọn mẹ̀kúnnù ní kẹ́ṣẹ́ inú láti wá ìtẹ̀síwájú àti ìdàgbàṣókè àwùjọ. Èyí ló gún Fanon (1967) àti Ngugi wa Thiongo (1986) ní kẹ́ṣẹ́ inú tí wọ́n fi ṣe àlàyé pé

> Àṣà tó ṣe e tẹ̀lé, àṣà tó ṣe é fi yangàn lójú abínú ẹni, irú àṣà bẹ́ẹ̀ ló yẹ kí òǹkọ̀wé máa ṣe àwárí àti àfihàn nínú iṣẹ́ ọnà rẹ̀.

Thiongo sọ pé nípa lílo èdè abínibí fún kíkọ́ lítíréṣọ̀, à ń gbé àṣà láruge ni. Ó ní ẹni tí à ń bá jà, tí a sì ń lo èdè rẹ̀, a ò le borí rẹ̀, à fi tí a bá lo èdè tiwa tó kún fún àṣẹ àti agbára.

**Kókó Inú Ewì Èwe Ìwòyí**

Ìwé Ewì Àfàìmọ̀ àti àwọn Àròfọ̀ Mìíràn tí òǹkọ̀wé Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ jáde sí orí àtẹ ní ọdún 1978, ìwé náà jẹ́ ọ̀kan pàtàkì tí a tẹ̀ jáde lórí ewì ìwòyí. Oríṣìíríṣìí àwọn nǹkan tó ń ṣẹlẹ̀ lóde òní ni àwọn ewì inú ìwé náà dálé. Àwọn ewì náà kọ́ ni lẹ́kọ̀ọ́, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀pọ̀ sì ń dẹ́rìn-ín pani. Ewì Èwe ìwòyí wà ní ojú ewé mẹ́ta dín-lọ́gọ́ta dé ojú ewé mọ́kànlélọ́gọ́ta (57-61), ìlà méjìdínláàdóje (128) ni gbogbo ewì náà jẹ́. Kókó ohun tí ewì náà dálé ni ìgbélárugẹ ohun tí ó jẹ́ tiwa-n-tiwa, ṣé Yorùbá bọ̀ wọ́n ní tẹni-n-tẹni, tàkísà ni ti àtàn. A rí i pé akéwì náà ń tẹ̀lé èrò bí àtúnṣe yóò ṣe wà nínú àwùjọ wa ni.

## ÌTÚPALẸ̀ EWÌ ÈWE ÌWÒYÍ PẸ̀LÚ TÍỌ́RÌ ÀṢÀ ÌBÍLẸ̀

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, pé àwọn tí wọ́n ṣe agbátẹrù tíọ́rì àṣà, wọ́n rí àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun atáyéṣe tí ó máa ń tẹ̀síwájú, àṣà kò gbọdọ̀ dúró lójú kan bí omi adágún, ṣùgbọ́n iṣẹ́ lítíréṣọ̀ gbọdọ̀ ṣetán láti dá àábò bo àṣà abínibí. Ògúnṣínà (1987) tilẹ̀ sọ pé ìṣẹ̀ṣe ní èdìdì lítíréṣọ̀ Yorùbá, nítorí náà ìwé lítíréṣọ̀ tí kò ní àṣà nínú kì í ṣe lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ìdí nìyí tí àwọn kan fi rí lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí ilé ìṣúra tàbí ilé tí à ń kó àwọn nǹkan ìsẹ̀nbáyé sí.

Nínú ewì Èwe Ìwòyí, oríṣìí àṣà tó súyọ ni èdè, oge ṣíṣe, oúnjẹ jíjẹ, lítíréṣọ̀ alohùn àti iṣẹ́ ìsẹ̀nbáyé. Akéwì jẹ́ kí á mọ̀ pé gbogbo àwọn àṣà yìí ni àkóbá ti dé bá lọ́dọ̀ àwọn

èwe ìwòyí. Ó ní ọ̀pọ̀ nínú wọn ni kò lè sọ Yorùbá láì má ṣe àmúlò èdè Gẹ̀ẹ́sì, bí àpẹẹrẹ, ó ní:

Ní ojú ewé kẹtàdínlọ́gọ́ta, akéwì náà lòdì sí àmúlùmálà èdè tí àwọn èwe ìwòyí kúndùn láti mọ́ lò. Ó ní:

Wọ́n á ní onkúlú

Bí wọ́n wòyá sùnsùn

Wọ́n á pè é ní mọ́mì

Bàbá tó ń tiraka fún wọn lóúnjẹ

Bàbá náà wáá di dádì ọ̀sán gangan.

o.i. 59, ìlà 5-9

Akéwì fẹ́ jẹ́ kí àwọn èwe ìwòyí dúró lójú kan lórí ìlò ède wọn, kí wọ́n máa lo èdè Gẹ̀ẹ́sì papọ̀ mọ́ èdè Yorùbá. Akéwì náà tún ṣe àfihàn ọ̀sẹ̀ tí tẹlifíṣàn àti rédíò ṣe nínú ayé àwọn èwe ìwòyí, à ti pé ilé sinnimọ́ ní wọ́n ti ń kọ́ àwọn ìwà burúkú.

Akéwì ṣe àpèjúwe àwọn Yorùbá ayé àtijọ́ bí wọ́n ṣe ń wọ aṣọ, irun dídì, bàtà wíwọ̀, lààálì lílé, osùn kíkùn. Ṣùgbọ́n akéwì jẹ́ kó yé wa pé ojú ará oko ni àwọn Èwe Ìwòyí fi máa ń wo ẹni tí kò bá múra bí i tiwọn nínú àwùjọ wa. Akéwì ṣe àfihàn èyí, ó ní:

Ẹ̀wù abínibí tíí buyì kéèyàn

Èyíun ni kò jẹ́ dọ́rùun ti wọn

Àf'ẹ̀wù àjèjì tí ò bokùn tààrà

o.i. 57, ìlà 32-34

Akéwì tako àṣà aṣọ wíwọ̀ ìgbàlódé, èyí tí ó máa kó ọmú sókè, èyí tí ó fi ìdí àti ayà sílẹ̀, ètè kíkùn bí ti eegun, ìlò irun wîigì, bàtà ẹlẹ́nu tínrín, tó lè rọ́ni lọ́rùn ẹsẹ̀, bẹ́ẹ̀ náà ló tako àṣà ṣòkòtò wíwọ̀ fún obìnrin, ara bíbó, ojú ni fanta, ẹsẹ̀ ni kóòkì èyí tó wọ́ pọ̀ nínú àwùjọ wa. Akéwì jẹ́ kí á máa pé èyí kò buyì fún ọmọlúàbí. Ó sì ń pè fún àtúnṣe.

Bákan náà, akéwì fẹ́ kí á mọ̀ pé tí a bá fi le ṣe ìgbélárugẹ àwọn ohun t'ó jẹ́ tiwa-n-tiwa ètò ọrọ̀-ajé wa yóò gbèrú sí i. Ìdí nìyí tí ó fi sọ pé:

Ṣé ẹ kò mọ̀ pé bá a tọ́jú àṣà
Ó lè mówó wálé
Owó tá a fi ra wîigì ó ní dúró ní Nàìjíríà

o.i. 58, ìlà 49-51

Èyí túmọ̀ sipe, ṣíṣe ìgbélárugẹ àṣà àwọn ẹ̀yà mìíràn, níse ni a ń gbé ètò ọrọ̀-ajé wọn lárugẹ. Tí à ń rẹ tiwa nílẹ̀. Akéwì jẹ́ kí á mọ èyí, nígbà tí ó sọ pé:

Ẹni tó ń lo nǹkan ilẹ̀ yìí
Ló ní kílẹ̀ yìí
Ó lówó lọ́wọ́
Ẹni tó ń lohun òkèèrè ń sọwó nù ni.

o.i. 58, ìlà 57-58

Akéwì náà gbà pé, kò sí ohun tó burú nínú lílo àṣà aláṣà, ṣùgbọ́n èyí tó bá dára nínú àṣà aláṣà ló yẹ kí á mú lò, kí á tako àwọn àṣà àtọ̀húnrìnwá, èyí tó lè ṣe àkóbá fún ni,

bí a bá ṣe ń lo àwọn àṣà àjèjì tó dára, kí á má gbàgbé àwọn àṣà ìbílẹ̀ wa, kí á sì gbìyànjú láti ta àwọn àṣà tiwa náà fún àwọn àtọ̀húnrìnwá. Akéwì ní:

> Bá a bá ràsà alásà díẹ̀
>
> Ǹjẹ́ kò yẹ k'áwa náà ó le ta tiwa
>
> Ẹ wá jẹ́ bí arungún ọmọ gbogbo
>
> o.i. 60, ilẹ̀ 102-104

Bákan náà, akéwì dárúkọ lára àwọn iṣẹ́ ìsẹ̀ntáyé àwọn àṣà Yorùbá nínú rẹ̀ ni iṣẹ́ Àgbẹ̀ àti Ẹja pípa. Akéwì náà lo ìbéèrè pèsìjẹ láti fi bèèrè lọ́wọ́ àwọn èwe ìwòyí, ó ní:

> Ó lè roko bí, bó bá dinú igbó?
>
> Ó lè dẹ̀gèrè fẹ́ja lálẹ̀ odò?
>
> o.i. 57, ìlà 20-21

Iṣẹ́ oko ríro àti ẹja pípa ni akéwì gbéyọ síta. Ní òde-òní, kò síomo, oko mọ, gbogbo ọmọ oko ló fẹ́ darí sínú ìlú ńlá, bẹ́ẹ̀ sì ni ọmọ ìgboro kò fẹ́ lọ sóko, èyí sì ń fa àkóbá ńláńlá fún àṣà iṣẹ́ abínibí Yorùbá àti èrò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè wa.

Akéwì náà tẹ̀síwájú láti jẹ́ kí á mọ̀ pé àwọn èwe ìwòyí, oúnjẹ inú agolo ni wọ́n fẹ́ràn ni jíjẹ jù. Ó jẹ́ kí á mọ̀ pé ọ̀tọ̀ ni ifá, ọ̀tọ̀ ni fáìlì, ìyẹn ni pé a kò le fi àwọn oúnjẹ yìí wé àwọn oúnjẹ ìbílẹ̀ Yorùbá bí i Iyán, Àmàlà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, àti pé àǹfààní pọ̀ nínú oúnjẹ ìbílẹ̀ Yorùbá. Ó ní:

> Ẹ̀yin ò kúkú maànfààní ká lágbádá àti bùbá

Ká jiyán ká mẹmu yàtọ̀ sóúnjẹ inú agolo.

o.i. 58, ìlà 55-56

Akéwì náà fi èdè tó lóòrìn gbé àwọn àṣà tó súyọ nínú ewì rẹ̀ náà kalẹ̀, ó jẹ́ kí á mọ ọṣẹ́ tí àṣà àtọ̀húnrìnwá ń ṣe lórí àṣà Yorùbá láti ọ̀dọ̀ àwọn èwe ìwòyí. Èrò akéwì ni pé, kí àwọn èwe ìwòyí padà sí ẹsẹ̀ àárọ̀, nítorí pé àtẹ́wọ́-labálà, èyí tó bá dára nínú àwọn àṣà àtọ̀húnrìnwá kí a mú mọ́ra, èyí tí kò bá dára tí ó lè ṣe àkóbá fún àṣà wa, kí á dàá nù bí omi ìsanwọ̣.

## ÌLÒ ÈDÈ INÚ EWÌ ÈWE ÌWÒYÍ

Èdè akéwì náà pegedé, ó sì lọ tààrà. Ó lo èdè ní ọ̀nà tó wuyì, tó sì wúni lórí. Akéwì ṣe àmúlò àwọn ọnà èdè lóríṣiríṣi ní ọ̀nà tó bá iṣẹ́ tó fẹ́ jẹ́ fún àwọn èwe inú àwùjọ mu. Ó ṣe àmúlò Àwítúnwí, Àfiwé tààrà, Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, Àsọdùn, Òwe, Ọ̀rọ̀ àyálò, Ìtakora abbl.

### Àwítúnwí

Àwítúnwí ni ohun tí à sọ lẹ́ẹ̀mejì, ẹ̀ẹ̀mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Àwítúnwí yìí ni a fi ń tẹpẹlẹ mọ́ kókó kan láti pe àkíyèsí sí ohun tí ó bá múmú láyà akéwì. Ṣé alágbẹ̀dẹ tó ń lu ìrìn lójú kan, ó ní ohun tó rí ni. Akéwì ń fẹ́ àtúnṣe lórí ohun tí ó tẹnumọ́ ni. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà là ń gbà ṣe àwítúnwí, ó lè jẹ́ ẹyọ ọ̀rọ̀, àkùdé, ó sì tún lè jẹ́ àwítúnwí gbólóhùn.

### Àwítúnwí Ẹyọ Ọ̀rọ̀

Àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀ wáyé ní ìlà 2, 3, 27, 28, èyí tí ó ń tọ́ka sí àwọn "Èwe Ìwòyí".

<u>Wọ́n</u> sewe nínú bí ẹyẹ

Wọ́n ṣe kókósẹ̀ bí ẹran ẹ̀ẹ̀dẹ́gbẹ̀ta

Wọ́n a máa ṣe bí alákọra

Wọ́n a f'èdè òyìnbó bí ẹni a dì lọ́rùn.

Àwọn ọ̀rọ̀ tí a fàlà sí nìdìí ni àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀.

**Àwítúnwí Àkùdé Gbólóhùn**

Àwítúnwí Àkùdé gbólóhùn náà kò gbẹ̀yìn nínú ọnà èdè tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá lò láti fi dámi ọbẹ̀ rẹ̀ léná nínú ewì "Èwe Ìwòyí". Èyí tó túmọ̀ sí pé àwọn èwe ìwòyí kò le ṣe ohunkóhun bí àwọn ará àtijọ́, àti pé wọn kò ní òye iṣẹ́ ìsẹ̀ǹbáyé Yorùbá kankan. Bí àpẹẹrẹ:

Ẹni tó ń lọ ... ìlà 57 àti 58.

Bó o bá ... ìlà 53, 64 àti 87

Òyìnbó tó ń ... ìlà 43, àti 62

Wọ́n a ... ìlà 35, 36 àti 37

**Àwítúnwí Gbólóhùn**

Àwítúnwí gbólóhùn kò fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ nínú ewì "Èwe Ìwòyí". Àkọlé ewì náà gan-an ló jẹ́ àwítúnwí gbólóhùn, torí pé a bá pàdé nínú ewì náà, bí àpẹẹrẹ:

Èwe Ìwòyí ... ìlà 98 àti 127

**Àfiwé Tààrà àti Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́**

Àfiwé ni Ọpẹ̀fẹ̀yítìmí (1997) pè ní "Àwòrán inú". Ó ní lára àbùdá ènìyàn ni láti ṣẹ̀dá nǹkan tuntun lára èyí tí wọ́n mọ̀ tẹ́lẹ̀. Ìṣọ̀lá lo onírúurú àfiwé nínú ewì Èwe Ìwòyí.

**Àfiwé Tààrà**

A rí àfiwé tààrà ní ìlà

Wọ́n sewe nínú bí ẹyẹ ... ìlà 2

Wọ́n ṣe kókósẹ̀, bí ẹran ẹ̀ẹ̀dẹ́gbẹ̀ta ... ìlà 3

Wọn a f'èdè òyìnbó bí ẹni a dì lọ́rùn ... 28

Wọn á rí bí i jáwé jura ... ìlà 35.

**Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́**

A rí àpẹẹrẹ àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ ní ìlà 54. Ó ní:

Àsà baba rẹ̀ ló dì máyà ... ìlà 54

**Àsọdùn**

Àsọdùn ni mímú kí ohun tí kò le sè ká ní ó ṣe é ṣe, akéwì lo àsọdùn nínú ewì Èwe Ìwòyí, ṣùgbọ́n lílò tó lo ọnà èdè náà kò fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀. A rí àpẹẹrẹ àsọdùn ní ìlà 93, ó ní:

Gbogbo ọlọ́sẹ̀ òyìnbó kò ní sùn...

Kò ṣe é ṣe fún ọlọ́sẹ̀ kó má sùn, torí wọn kò mú ènìyàn ní túláàsì láti ràá.

**Òwe**

Òwe ṣe pàtàkì sí ìran Yorùbá tó bẹ́ẹ̀ tí wọ́n rò pé ọ̀rọ̀ sákálá ni ọ̀rọ̀ tí kò lówe nínú. Pàtàkì òwe àti ìwúlò rẹ̀ láàárín Yorùbá ni Ọlátúnjí (1987:170) ṣàlàyé pé: Òwe Yorùbá ń ṣe àfihàn ìwé ọmọlúàbí tó jẹ́ ìtẹ̀wọ́gbà fún àwùjọ, ó sì ń bẹnu àtẹ́ lu ìwé ìbàjẹ́ tí àwùjọ lòdì sí. Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé Ọlátúnjí lòdì sí ìwà ìbàjẹ́. Ìṣọ̀lá fi òwe rẹ̀ pè fún ìfura ìwà ìbàjẹ́ tó gbokùn láàárín èwe ìwòyí, kí á má ṣe rò pé ohun rere ni wọ́n ń ṣe. Akéwì kò ṣe àmúlò òwe púpọ̀ nínú ewì èwe ìwòyí. Ó ní:

Ọ̀gẹ̀dẹ̀ ń bàjẹ́, ẹ ní ó ń pọ́n ... ìlà 10

Akéwì náà lo òwe ní ọ̀nà tó mọ́gbọ́n dání, àti ní ààyè tó yẹ.

**Ìbéèrè Pèsìjẹ**

Ara ètè kíkọjú sí òǹkàwé kéwì ní ìbéèrè pèsìjẹ jẹ́. Ìbéèrè tí akéwì bèèrè láìjẹ́ pé òun pàápàá kò mọ ìdáhùn tí kò sì retí èsì láti ọ̀dọ̀ òǹkàwé rẹ̀ ni ìbéèrè pèsìjẹ jẹ́. Bí àpẹẹrẹ nínú ewì Èwe Ìwòyí, ó ní:

Taa lọmọ ìwòyí ń f'ojú òpè é wò? ... ìlà 1

Só tán àbó kù? ... ìlà 18

Àbí tẹni kí tẹni ... ìlà 23

Kín ló kúkú ṣe yín té ò le è fura? ... ìlà 42

Òyìnbó tó ń sòwò, ẹ rò pó gọ̀? ... ìlà 43.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìbéèrè yìí ni akéwì fúnra rẹ̀ wá ìdáhùn sí. Lílo ìbéèrè pèsìjẹ wọ̀nyí lóòrèkóòrè nínú ewì mú kí òǹkàwé kópa nínú ewì kí ó sì máa fọkàn bá a lọ.

**Ọ̀rọ̀ Àyálò**

Àwọn Yorùbá ló pèdè pé odò tí kò fomi olómi kúnra ó ṣetán àtigbẹ, Ìṣọ̀lá lo èdè àyálò nínú ewì rẹ̀. Gbogbo àwọn èdè tó yalo ló ti wọ inú èdè Yorùbá. Ìdí níyì tí ó fi ṣe àyálò wọn wọ inú ewì rẹ̀.

| **Ọ̀rọ̀ Àyálò** | **Èdè Yorùbá** | |
|---|---|---|
| Uncle | Ọnkulu | ìlà 5 |
| Mummy | Mọ́mì | ìlà 7 |
| Daddy | Dáádì | ìlà 9 |
| Radio | Rédíò | ìlà 16 |
| Television | Tẹlifísàn | ìlà 15 |
| Wig | Wîìgì | ìlà 50 |
| Record | Rẹ̀kọ́ọ̀dù | ìlà 59 |
| Monkey | Mọnkí | ìlà 66 |
| Tie | Táì | ìlà 68 |
| Cinema | Sinimá | ìlà 80 |

Gbogbo àwọn àmúlò ọnà èdè wọ̀nyí ló mú ewì náà dùn, tí ó sì bu ẹwà kún iṣẹ́ rẹ̀. Àwọn ìlò èdè yìí fi akéwì hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó mọ ohun tó ń lọ ní àwùjọ, ó sì jẹ́ k í á mọ̀ pé bí àṣà Yorùbá ṣe káṣẹ̀ kan rọ̀, káṣẹ̀ kan dúró kò dùn mọ́ akewininu. Ní ṣókí gbogbo ìlò èdè yìí fi akéwì hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ní ìmẹ̀sọ́ ọ̀rọ̀ Yorùbá.

**Àgbálọgbábọ̀**

Nínú bébà yìí, a ṣe àmúlò tíọ̀rì àṣà ìbílẹ̀ láti fi ṣe ìtúpalẹ̀ ewì *Ewì Ìwòyí* tí Ìṣọ̀lá kọni ọdún (1978). Iṣẹ́ yìí rí àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó máa ń dàgbà sókè, ṣùgbọ́n tí ọ̀làjú àti ẹ̀sìn atọ̀húnrìnwá, ẹ̀kọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tí ṣe àkóbá fún àṣà abínibí ilẹ̀ Yorùbá ní ọ̀dọ̀ àwọn èwe ìwòyí. Àpilẹ̀kọ yìí pé àkíyèsí àwọn òbí, alágbàtọ́ àti olùkọ́ pé kí wọ́n mú àṣà Yorùbá ní ọ̀kúnkúndùn, kí wọ́n kọ́ àwọn ọmọ àti akẹ́kọ̀ọ́ ní àṣà abínibí ilẹ̀ wa. Ṣé Yorùbá bọ̀ wọ́n ní "ọmọ kò ní bá ìpèlé ìyá rẹ̀, kó sí aṣọ dá".

## ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adéoyè, A.A. (2001). Ìfáàrà lórí àwọn àṣà ilẹ̀ Yorùbá. Nínú Ọ̀pádọ̀tun Túnjí (Olóòtú). *Àkójọpọ̀ ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ Yorùbá, Apá kejì.* Ọ̀yọ́: Ọ̀yọ́ State College of Education Publication Series.

Adéyẹmí, L. (2006). *Tíọ̀rì lítíréṣọ̀ ní èdè Yorùbá*. Ìjẹ̀bú Òde: Shebíotimọ Publications.

Àjàyí, B. (1998). *Òjìlélẹ́gbẹ̀ta àló àpamọ̀ Yorùbá*. Ìlọrin: Tawfiquallahi. Publishing House.

Fanon, F. (1967). *The Wretched of the Earth*. England: Pengun Book.

Ìṣọ̀lá, A. (1978). *Àfàìmọ̀ àti àwọn àròfọ̀ mìíràn*. Ìbàdàn: University Press Ltd.

Ògúnṣínà, B. (1987). *Òǹkọ̀wé Yorùbá àti ìdàgbàsókè orílẹ̀-èdè Nàìjíríà*. Ifẹ̀: Annals of the Institute of Cultural Studies (2).

Ọpẹ́fẹ̀yìntìmí, A. (1997). *Tíọ̀rì àti ìsọwọ́lò èdè*. Òṣogbo: Tanímẹ̀yìnọ̀la Press.

Rájí, S.M. (1993). *Ìtúpalẹ̀ èdè, àṣà àti lítíréṣọ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn: Fountain Publishers.